## April 2021

### Agbára Gbọ́dọ̀ pàrọ̀ ọwọ́

**ORIN:**

**<u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>**

1. Olùṣẹ̀dá ìgbèkùn, tó fi mí sínú ìgbèkùn, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, àkókò rẹ ti dópin lónìí, nípa agbára nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.
2. Ògo náà, tí ọ̀tá ń fi pamọ́ fún mi, pé ń kò ní lò nígbà ayé mi, aǹgẹ́lì Ọlọ́run, lọ sí orígun mẹ́ẹ̀rin àgbáyé, kí o sì gbà á fún mi lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Màjẹ̀mú ìkà, tí a yàn láti jẹ́ kí ń máa ṣiṣẹ́ fún àwọn ọ̀tá, má a fọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára yówù, tí a yàn láti so mí pọ̀ mọ́ ìgbèkùn àjèjì, mo kọ̀ ẹ sílẹ̀ lónìí, kú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìsòro, láti ìpele òkùnkùn, tí a yàn láti jẹ́ kí n rìn wọnú jàǹkárìwọ̀, máa di píparun nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Ìwọ àpáta àti ibi gíga mi, dìde kí o sì di ibi ààbò mi kúrò lọ́wọ́ jíjà ìjì tí àwọn ọ̀tá tí sèto rẹ̀ fún mi lọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ìwọ ọ̀run, gbọ́ ohùn Olúwa, kó ara rẹ jọ papọ̀, kí o sì fi ìgbéga mi sọwọ́ sími lónìí, ní orúkọ Jésù.

**<u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍÍDÌ 91</u>**

1. Ọlọ́run, dìde, kí o sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn, sínú Orí òkè iná àti ìṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí, bà lé Orí òkè iná àti iṣẹ́ ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run àánú àti agbára, tẹjú mọ́ ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Ọfà òkùnkùn, tí kìí jẹ́ kí ohun rere pẹ́ nínú ayé mi, túká kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹni yówù, tó ń gbẹ́bọ, láti fi ayé mi sòfò, di ìfisòfò, ní orúkọ Jésù.
6. Ọfà òkùnkùn, tí a yàn láti sọ mi di adẹ́tẹ̀ ètò ìsúná, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára, tó n yan ọjọ́ ikú àti ìsìnkú fún ayé mi, kú lòjijì, ní orúkọ Jésù.

**ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ**

**2 kọ́ríntì 2:14** Ṣùgbọn ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹni tó ń yọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbà gbogbo nínú krísítì, tí ó sì ń fi òórùn ìmọ̀ rẹ̀ hàn nípa wa níbi gbogbo.

**1 kọ́ríntì 15:55** Ikú, oró rẹ dà? Iṣà òkú, ìṣẹgun rẹ dà?

**Jóṣúà 10:8** Olúwa sì wí fún Jóṣúà pé, máṣe bẹ̀rù wọn: nítorí tí mo ti fi wọ́n lé ọ lọ́wọ́; kí yóò sí ọkùnrin kan tí yóò le dúró níwájú rẹ.

**Ìfihàn 12:11** Wọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀-ọ̀dọ́ àgùntàn náà, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, wọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Hébérù 4:12** Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yè ó sì lágbára, ó sì mú ju idàkídà olójú méjì lọ, ó sì ń gúnni àní títí dé pípín ọkàn àti ẹ̀mí níyà, àti oríke àti ọ̀rá inú egungun, òun sì ni olùmọ̀ èrò inú àti ète ọkàn.

**Fílípì 4:13** Èmi lè ṣe ohun gbogbo nínú krísítì ẹnití ń fagbára fún mi.

**Róòmù 8:1** Ǹjẹ́ kò sí nísinsinyìí fún àwọn tí o wà nínú krísítì Jésù, àwọn tí kò rìn nípa ara bíkòṣe nípa ti ẹ̀mí.

**Róòmù 8:28** Àwá sì mọ̀ pé ohun gbogbo li ó ń ṣiṣẹ́ pọ̀ sí rere fún àwọn tí ó fẹ́ Ọlọ́run, àní fún àwọn ẹnití a pè gẹ́gẹ́ bí ìpínnu rẹ̀.

**Jòhánù 16:33** Nǹkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fún yín tẹ́lẹ̀, ayé, ẹ̀yin ó ní ìpọ̀njú; ṣùgbọ́n ẹ tújúká, mo ti ṣẹ́gun ayé.

**Òwe 10:28** Àbá olódodo ayọ̀ ni yóò jàsí: ṣùgbọ́n ìrétí ènìyàn bùburú ni yóò ṣègbé.

**1 Johánù 5:5** Tani ẹni tí ó ṣẹ́gun ayé, bí kò ṣe ẹni tí ó gbàgbọ́ pé Ọmọ Ọlọ́run ni Jésù íṣe?

**1 Johánù 4:4** Ẹyin ọmọ mi, ti Ọlọ́run ni ẹ̀yin, ẹ̀yin sì ti ṣẹ́gun wọn: nítorí ẹni tí ń bẹ nínú yin, tóbi ju ẹni tí ń bẹ nínú ayé lọ.

**Jòhánù 1:5** Ìmọ́lẹ̀ náà sì ń mọ́lẹ̀ nínú òkùnkùn; òkùnkùn náà kò sì borí rẹ̀.

**2 kóríntì 9:8** Ọlọ́run sì le mú kí gbogbo oore-ọ̀fẹ́ má a bísí i fún yin; kí ẹ̀yin, tí ó ní ànító ohun gbogbo nígbà gbogbo, lé máa pọ̀ sí i ní iṣẹ́ rere gbogbo.

**Jeremiah 29:11** Nítorí èmi mọ èrò tí mo rò sí yín, ní OLÚWA wí, àní ìró àláfíà, kì sì íṣe fún ibi, láti fún yín ní ìgbà ìkẹyìn àti ìrètí.

**Fílípì 4:19** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèṣè ní kíkún fún gbogbo àìní yín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ rẹ̀ nínú ògo nínú krísítì Jésù.

**Róòmù 15:13** Ǹjẹ́ kí Ọlọ́run ìrètí kí ó fi gbogbo ayọ̀ òhun àláfíà kún yín ní gbigbàgbọ́, kí ẹ̀yin kí ólè pọ̀ ní ìrètí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́.

**Orin Dáfídì 103:1-4** Fi ìbùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, àti gbogbo ohun tí ó wà nínú mi, fi ìbùkún fún orúkọ rẹ̀ mímọ́. Fi ìbùkún fún OLÚWA, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo oore rẹ̀: Ẹni tí ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ jì; Ẹni tí ó ti tán gbogbo àrùn rẹ; Ẹni tí ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìpárun; ẹni tí o fi iṣ`eun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ ní adé.

**Orin Dáfídì 16:11** Ìwọ yóò fi ipa ọ̀nà ìyè hàn mi, ní iwájú rẹ̀ ni ẹ̀kún ayọ̀ wà: ní ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ ni dídùn-inú wà láéláé.

**Orin Dáfídì 118:24** Èyí ni ọjọ́ tí Olúwa dá: àwa ó máa yọ̀, inú wa yóò sì máa dùn nínú rẹ̀,